Bibeli fun awon omode

# Jona ati Eja nla



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Jonathan Hay
Alastair Paterson

Olu'lo: Mary-Anne S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Opolopo odun seyin, okunrin ti oruko re n je Jona, ti o n gbe ni ile Isireli, ni ojo kan, Olorun so fun un ki o lo si Ninefe, ilu nla, ilu alagbara, ni gbogbo agbaye.



A so fun Jona ki o se ikilo fun awon ara ilu naa pe Olorun mo iwa buburu won.




Jona saigboran si Olorun! Kaka ki o lo si Ninefe, Jona gun oko oju omi lo si agbegbe keji kan ti a n pe ni Tasisi.

Oluwa Olorun si ran efufu lile sinu okun. Iji naa si dide! Awon atuko naa si beru boya oko naa le fo meji ko si ri.



Iji naa n buru jojoo si, pelu ijaya, awon atuko gbadura si Olorun won, won si ko eru won da sinu okun ki oko won le fuye, sugbon ko si nnkan ti o ran won lowo.



Jona nikan ni o wa ni ninu oko ti ko gbadura kaka bee, o dubule o si sun, o sun wora. “Olori oko naa to o wa, kin ni iwo n se ti o sun? Dide soke! Gbadura si Olorun re! Boya Olorun yoo ro ti wa, ki awa ki o maa baa segbe.”



Awon atuko naa ro leyin o reyin, pe wahala to de baa won yii ni nnkan se pelu Jona. O so fun won pe o n sa kuro niwaju OLUWA ni. Won beere pe "kinni ki a se si o, Nitori ki okun le dake je e? E gbe mi, ki e si ju mi sinu okun." Jona da won lohun. "Nitori emi mo pe nitori mi li efuufu lile yii se de bayin."



Awon atuko ko fe e
ju Jona sinu okun.
Nitori naa won ja
oko naa wale,
sugbon won kori
ohun kan, se,
ohun kan ni o
ku lati se.



Leyin adura fun idariji ese, awon atuko gbe Jona soke, won gbe e so sinu okun. Bi Jona se poora sisale okun naa si dake je, iji naa si dawo duro. Ayipada ojiji oju orun na ba awon atuko leru ju ti iji lo. Won gbodo mo wi pe Olorun ni kan lo le se eyi. Ni eru ati iyanu won sin OLUWA.



Ni akoko naa, alaigboran iranse naa ri iyalenu nla. Lanireti ori sinu okun, jona mo wi pe ko si ohun ti o le gba oun la ninu re, oun gan an iba ti ri - sugbon Olorun ni ona miiran fun un.



OLUWA ti seto eja nla lati gbe Jona mi. Eja naa rin si asiko. O sere kan ati pe Jona jade lati inu okun lo si inu eja. Jona wa ninu eja yii fun ojo meta. O ni akoko ti o po lati ronu ati lati gbadura.



Leyin ojo meta, Jona seleri lati gboran si sOlorun.
Ni bayii, Olorun so fun eja, o si po Jona si eti okun.



Leekan si, Olorun so fun Jona ki o lo si Ninefe ki o waasu oro Olorun. Nigba yi, Jona lo, Jona wo ilu, o n kigbe "Ni ogoji ojo a o ja ninefe gba."



Awon ara Ninefe gba oro Olorun gbo. Won lo lai jeun, won wo aso ofo lati fihan Olorun pe awon bebe, fun idariji ese won, koda oba re ara re sile niwaju Olorun. O bo aso igunwa re sile, o wo aso ofo, o si joko ninu eeru. O pase ki gbogbo eniyan ki o yipada kuro iwa buburu ati aisedede won, ki won si gbadura ki Olorun ko darijin won.



Olorun darijin won, o je ojo iyanu, ojo ayo ni Ninefe nigba ti awon eniyan naa mo pe Olorun ti darijin won. Sugbon inu n bi enikan. Jona!





Kin ni idi ti inu fi mbi Jona? O so fun Olorun, "Emi mo pe Olorun Oloore ofe ni O ati alaanu, o lora lati binu, olopo iyonu si ni O." Ni oro miiran, Jona mo pe Olorun a maa dariji eni ti o ba bebe fun idariji ati eniti o gboran si ase Olorun ati oro Olorun. O dabii eni pe Jona ko feran awon ara ilu Ninefe. ko fe ki a dariji won.

Inu bi Jona gidigidi si Olorun ti o fi so pe “Gba emi mi kuro lowo mi”, Nitori iku san ju ki n we laaye lo.



Jona joko leyin odi ilu, o duro wo ohun ti Olorun yoo tun se. Oluwa Olorun pese itakun pelu ewe ni nla. O dagba kiakia, lati siji bo Jona kuro lowo orun gbigbona ni gbogbo ojo.



Ni aaro ojo keji, Olorun ran kokoro lati pa itakun naa. Nigba naa, Oluwa si pese oorun gbigbona, efuufu lile sori Jona titi o fi ronu lati ku. Gbogbo eleyii mu inu tubo bi Jona si.




Nigba naa ni Oluwa so fun Jona pe, "N je o to fun o lati binu? Iwo kedun itakun naa, nitori eyi ti iwo ko sise re beeni iwo ko si muu dagba. Ti o hu jade ri oru kan, ti o si ku niasale kan. Nitori kinni ki Emi o
ma se saanu Ninefe, ilu nla ni, pelu awon eniyan egberun inu re."

Jona ati Eja nla

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

iwe Jona

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.